# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 753, SATURDAY, JULY 25, 1964 (2D)


## Egbe Afenifere Yio Se Ipade Loni

AKURE:— Ni oni Abamate ti ise ojo ukedogbon osu yi ni awon omo egbe Afenifere jakojade ekun ndo yio se ipade nla kan ni ile ise awon omo egbe na n Erekesan ni Akure.

Dokita S A Aluko ti o je akowe ti o pe apejo ipade na fi ye oniwe irohin wa ni ibadan pe gbogbo awon omo egbe to je asoju ni Ile Igbimo asofin, Alakoso ninu egbe Afenifere, awon Olori egbe Afenifere ni ekun Ondo ati awon enia meji lati ekun Ondo nibiti nwon ti ni awon asoju si ni ile igbimo asofin ipinle Iwo Orun tabi ti apapo Ijoba ile Naijiria ni yio wa sibi ipade na.

Dokita Aluko tun so ninu oro re ni Ibadan lana fun awon oniwe irohin pe opolopo oro ni awon omo egbe na yio fenukan ninu ipade oni na.

Dokita S A Aluko tun fi ye awon oniwe irohin pe ninu awon nkan ti awon omo egbe na yio fi enu kan ninu ipade oni yio jemo nipa nkan to nsele ni Ipinle Iwo Orun bayi ati eto ti awon omo egbe na ti ekun Ondo yio se nipa idibo si ile Igbimo Asofin ti Apapo Ijoba to nbo yi ati nipa bi nwon yio se fi ogbon si ajumosepo egbe Alakuko ati Afenifere.

## Ijoba Ti Gbe Awon Omo Egbe Afenifere Mejo Kuro L'ogba Ewon Eko

# NWON PIN JAKANDE S'OGBA EWON KADUNA

EKO:— Awon enia mejo ninu awon Olori egbe Afenifere ti ile ejo giga julo ko ebe ewon ti ile ejo kekere gbe won si ni ojo kini osu keje odun yi fun esun idite si apapo Ijoba ile Naijiria ati imo lati gbogun ti Oba binrin Geesi eyiti ile ejo kekere gbe awon enia na s'ewon ninu odun to koja ni irohin tu nfi ye wa pe awon enia mejo ninu won ni Ijoba ti pin si ogba ewon ni Ipinle Ariwa ati Ila Orun Naijiria ni ojo'Bo ti ise ojo ketalelogun osu yi.

Enia marun ninu awon to wa lo'gba ewon ni nwon gbe kuro l'ogba ewon Eko ti nwon gbe won lo si awon Ogba ewon ni ipinle Ila Orun Naijiria awon enia meta ni nwon gbe lo si Ogba ewon ni ipinle Ariwa

Eyi ni Oruko awon ti Ijoba gbe lo si ipinle Ariwa ni Lateef Jakande ti yio lo odun meje l'ogba ewon Samuel Otubanjo ti yio lo Odun meji l'ogba ewon ati Uzodinma ti o nlo odun marun l'ogba ewon. Awon enia meta na wa ni ogba ewon ti Kaduna.

Awon enia marun ti Ijoba gbe lo si Ipinle Ila Orun Naijiria ni Sebastian Umoren to yio lo odun meta l'ogba ewon, ati Simeon Oyeshile ti yio lo odun meji logba ewon awon mejeji yio wa ni ogba ewon ti Enugu

Michael Adedapo Omishade ti yio lo odun meje, Gabby Shasore odun marun ati Sunday Ebietoma yio lo odun meji logba ewon. Awon meteta yio se ewon won ni ogba ewon ti ilu Pota (Port Har Court)

Oloye Obafemi Awolowo ti yio lo odun mewa logba ni Ijoba ti tete gbe kuro logba ewon Eko ni ibere osu yi ti nwon si gbee lo si ilu Calabar lati lo se ewon re.



OLOYE OBAFEMI AWOLOWO



Samuel Onitiri



Lateef Jakande



Michael Omisade

### ONITIRI NI ILE IWOSAN

Eniti o je eni kewa ti o wa ninu ogba pelu awon omo egbe Afenifere yoku ni ogbeni Samuel Onitiri ni irohin fi ye wa pe o wa ni ile iwosan bayi fun ara re ti ko da.

Nigbati oniwe Irohin wa bere lowo Alakoso eto ogba ewon Oloye Giwa Omo Osagie pe kini idi re ti nwon fe ti gbe won kuro l'Eko?

Oloye Giwa Omo-Osagieso fun oniwe irohin wa lesi pe ohun to mu ki nwon fe gbe nwon kuro Logba ewon Eko ni pe fun eto to ti wa nile fun akoso ogba ewon.

WO OJU EWE KEFA

# ỌRỌ OLOTU

## Imọran Fun Gbogbo Olufẹ Awolọwọ

Nigbati awa oniwe Irohin Imọlẹ wo iwaju a t i ẹhin lati ọdun keji o le oṣu diẹ sẹhin ti a r i ohun gbogbo ti o nlọ ni orilẹ ede Naijiria ari pe ko si orin meji ti a tun le kọ bi kọṣe pe ki a tẹwọ adura si Oluwa Ọba alagbara julọ ki o t a wa nawọ ẹbe si awọn Alaṣẹ Ijọba apapọ Naijiria ki nwọn ba wa bu omi Ọlọrun mu ki nwọn mọ iya irora ati ibanujẹ ti Baba Olusẹgun ti njẹ bọ, ki iṣe fun ara tabi ẹbi rẹ nikan bikoṣe fun gbogbo ilẹ Naijiria

IYA WO LO TUN KU

Awa oniwe Irohin Imọlẹ tun nbere pe irufẹ iya wo lo tun ku ni ile aiye ti Baba Sẹgun ko ti jẹ larin ọdun meji yi? ninu asemọ ni Baba Sẹgun wa ti Sẹgun ti iṣe DAODU rẹ de ba lati ilu Oyinbo ti o jẹ pe nibi ti nwọn gbe nṣe Iwadi rogbodiyan n i Olusẹgun to lọ ki Baba rẹ ku ile, ninu ẹjọ kanna ni baba Sẹgun wa ti Sẹgun fi di ologbe laiku Erin a ki fi awọ rẹ se gbedu toto o ṣe bi owe.

Baba Ṣẹgun ko to de ibi oku ọmọ rẹogba ẹwon ni nwọn ti nlọ ki Baba Ṣ ẹ g u n ti a ba, ni ki a ma ba ọrọ yi lọ pupọ ni ọkan rẹ yio gbọgbẹ gẹgẹbi ti wa nihin

Nitori idi eyi awa oniwe Irohin Imọlẹ bẹ gbogbo olufẹran gidigidi pe ki ẹ jẹ ki a fi idakẹ rọrọ ma wo iṣẹ rere ti Oluwa yio ran si Olotu ilẹ Naijiria p e ki Arẹ Azikiwe wi laipẹ yi ni asiko iranti Ominira ninu oṣu kẹwa ọdun yi. Gbogbo ẹnyin ọmọ karọ o-jire mo afẹ ki ẹ ma gbọ agboye ọrọ kini itumọ ti gbogbo olufẹ Awolọwọ ni lati dakẹ jẹ?

Nitori idi eye a nfẹ ki ẹ jẹ ki ẹ jẹ ka fi idakẹ j ẹ ran ẹni wa lọwọ ati awọn ẹgbọn ati aburo wa ti nwọn njiya lọwọlọwọ bayi nitori awọn ọmọ karọ-o-jire ohunkohun ti a ba fẹ ṣe ẹ jẹ ki a wa ninu ile ẹgbẹ olukuluku ati ẹni kọkan wa.

Ki Oluwa ki o sọ asiwaju nibikibi ti o ba wa, ko si ẹniti abayọri idajọ Oloye Awolọwọ ko dun ṣugbọn idajọ ko lọ gẹgẹbi awọn ti nro Oluwa lo ma ẹjọ da ti ki ku sibi kan

FILA

Ewo ni ti fila ti awọn kan nde kakiri jasi eleyi papa tun fa ibanujẹ ba ọpọlọpọ awọn ẹbi Oloye Awolọwọ ati pe ti awọn enia kan ti ko ni iṣẹ lapa ba ti ri onjẹ jẹ yo nwọn yio ma pariwo kakiri ilu ti nwọn yio si ma kegbe Oloye Awolọwọ eleyi ko si fa nkankan wa rara bi ko ṣe pe ibanujẹ fun awọn ọta Awolọwọ.

Aro pe bi ẹ ba ranti ọrọ Alakoso ilẹ Naijiria Ọlọla Alhaji Abubakar sọ nigbati o lọ ri Arẹ ilẹ Naijiria Ọlọla Dokita Azikiwe pe ẹnikẹni to ba fẹran Oloye Awolọwọ pe ki olukuluku lo mu ẹnu wọ mọ.

Nitori idi eyi awa oniwe IroLin Imọlẹ bẹ gbogbo olufẹ Oloye Awolọwọ ki nwọn ma gba adura gidigidi fun Oloye Aw lọwọ pe yio pada bọ si ipo ọla la rẹ pẹlu Alafia. Awa oniwe Irohin Imọlẹ tun ki gbogbo ẹnyin olufẹ Awolọwọ pe ẹ ku idele rẹ. Awọn alagba lo ma npa lowọ pe "Ẹni to ṣe oju ko ṣe bi ẹni to ṣe ẹhin" Nitori eyi agba nyin ni imọran lati lọ kun fun adura fun idariji ẹbọ fun Oloye Awolọwọ.

# Ọtẹlẹmuyẹ Nki Nyin

Ẹku owurọ ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ ṣe dada la ji o? Ọrọ wa oni ko si pọ ṣugbọn mo fẹ ki ẹ ka a w ọ n iwuri ọrọ ti Ọgbẹni I B Odufọtẹ kọ nipa Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ati ẹgbẹ Afẹnifẹre

1 Awolọwọ ṣe 'lere o
omu sẹ Idahun ati egbe
O nna owo wa fun wa
O ṣe 'leri o
O fi owo kun o w o
cocoa wa
O ran ọmọ wa l' ẹkọ
ọfẹ o
O fi owo kun owo oṣiṣẹ o
O bojuto alafia ọmọ wa
O ya onisowo lowo wa
O dara pọmọ tẹru tọmọ
2 Bi a ba dibo fẹgbẹ ọlọpẹ
Bi a ba fibo wa fun ni
Ijọba,
Bi a ba fibo wa ṣe idajọ
3 Tani le ṣe bi Ẹ g b ẹ
Afẹnifẹre
Tani le ṣe bi ẹgbẹ Ọlọpẹ
Tani le ṣe to Ijọba bi
Awolọwọ
Tani le na owo wa fun
wa bi t'Awolọwọ
4 Tani o ran ọta rẹ lọwọ
Tani nfibi ṣu Olore ?
Tani ndina anfani ti a
ti ni
Tani pe Awolọwọ ko ṣe-
nre Tani tu awọn enia lara
5 Kilẹ yẹ ka, ṣe fun Awo
lọwọ,
Kilo yẹ ka se fun Ẹgbẹ
Ọlọpẹ Ka dibo wa fun
Bawo la le se gba Ijọba
fun Awolọwọ
Bawo lale se da silẹ kuro
l'Atimọle'o
Bi Ọlọpẹ ati awọn ọrẹ wọn
ba gba Ijọba.
Bi Ọpara pẹlu Awolọwọ ba
fimọ sọkan Idahun ati egbe
Bi a ba kọ ẹgbẹ Ọlọwọ silẹ
Ire-a-ka-ri o
Bi a ba mu ileri wa ṣẹ
Bi a ba gba ti Ọpara ati
Awolọwọ
Bi ẹgbẹ Akukọ ati Ọlọpẹ
ba s'otitọ
Bi awọn ẹgbẹ mejeji ba
s' ẹtọ fun wa
Ki Ọlọrun fi si wọn lọka
ki wọn mu 'eri sẹ -Amin

Bawo ni Ọbafẹmi Awolọwọ le ṣe mu ayipada rere wa ?

Bawo ni Ọbafẹmi Awolọwọ le ṣe ni agbara lati mu idera wa ba wa ?

Ẹ mura ọkan nyin silẹ fun idibo, ki ẹ si dibo fun Ọpẹ nigbati asiko ibo ba to Ibo nikan ni agbara; awọn ti wọn wa nibẹ nisisiyi ni agbara nitori ibo wa ti a di fun wọn ni ọdun karun sẹhin

Ibo nikan lo le gbe Ijọba le enia lọwọ Nitori eyi bi ẹ ba ti dibo fun Ọpẹ, ẹ ti dibo fun idasilẹ Awolọwọ On papa ti sọ eyi tẹlẹ O ni ki ẹ maṣe fi ija ran on lọwọ O ni ki ẹ fi ibo yin ran on lọwọ

Ṣe ẹnyin lẹ ma dibo fun on tabi on lo ma dibo fun yin ? Nitorina atimọle rẹ ko le di nyin lọwọ lati dibo fun un. Bi ẹ ba dibo fun Ọpẹ, ẹ ti dibo fun Ọbafẹmi Awolọwọ AWO ! AWO !! AWO !!!

TANI LE ṢE IJỌBA BI AWOLỌWỌ ? TANI LE ṢE IJỌBA BI ẸGBẸ AFẸNIFẸRE ?

O pin anfani kari gbogbo enia, ẹniti ko lowo lọwọ di olowo, ẹniti ko ni ẹkọ di Ọjọgbọn nipa iwe. Ẹniti ko riṣẹ di ẹniti o ngba enia si iṣẹ.

Ọba ti o sọ erufu di ẹgan ati Ọba ti o sọ Ẹgan di erufu, aiye ko ni gbagbe wọn. A ti wẹ tutu, a si wẹ gbigbona. Ewo lo ba ara wa mu o ? Ki ẹ ranti eyi lasiko ibo, ki ẹ dibo fun Ẹgbẹ Afẹnifẹre.

AWO ! AWO !! AWO !!!

## Si Gbogbo Ẹgbẹ Afẹnifẹre

KI Ẹ MAṢE BANUJE, KI Ẹ MAṢE NI IRẸWẸSI ỌKAN, BIKOTẸMILỌRUN BA TILẸ DA AṢIWAJU ẸGBẸ AFẸNIFẸRE LARE KO LE SI ANFANI KANKAN NINU EYI, A FI BI IJỌBA BA WA LỌWỌ RẸ

## E ma a Ka Irohin Imọlẹ Fun Itan Aladun

# Awọn Obinrin Ẹgbẹ Afẹnifẹre Ko Faramọ Idajọ Awolọwọ

EKO:- Ni ọjọ 'Ru ti ise ọjọ kẹsan Osu yi ni awọn obirin ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ẹka Eko sọ ninu ipade ti awọn ọmọ ẹgbẹ na se ni nwọn ti sọ ninu ọrọ wọn pe awọn kọ idajọ ile ẹjọ giga julọ ti ilẹ Naijiria silẹ fun ẹbẹ ti olori ẹgbẹ Afẹnifẹre Oloye Awolọwọ ti ile ẹjọ na kọ silẹ lori ẹsun iditẹ si Ọba birin Geesi ati ẹsun idoju Ijọba ilẹ Naijiria delẹ eyiti ile ẹjọ kekere kan fi ju Oloye Awolọwọ si ẹwọn Ọdun mẹwa ninu Ọdun to kọja



OLOYE ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Awọn ọmọ ẹgbẹ na sọ pe ọjọ nsun mọ ti gbogbo enia yio fi mọ pe awọn kọ idajọ ile ẹjọ na silẹ ati pe ti gbogbo enia yio mọ pe awọn wa lẹhin Awolọwọ

Ninu iransẹ ti awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre na fi ransẹ si Oloye Awolọwọ nwọn sọ pe awọn ni igbẹkẹle ninu Akoso rẹ.

Eyi ni ọrọ ti awọn ọmọ ẹgbẹ na fi ransẹ si Olori ẹgbẹ na, Oloye Awolọwọ "Awa Obinrin ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ẹka Eko fi nye ẹ pe awa wa lẹhin rẹ lọjọkọjọ. Iwọ ti ja fun eto ilọsiwaju ilẹ Naijiria osi ti sẹgun ama si ti ka ọ kun awọn olori ilẹ Afrika gẹgẹbi ẹni toja fun ilu rẹ ati fun eto ominira ilẹ Naijiria Awọn ọmọ ẹgbẹ na tun fi ye oloye Awolọwọ pe Asiko ti yio di Alakoso ilẹ Naijiria si ti suumọ ti pe o da awọn loju pe on ni yio se akoso ilẹ wa, Naijiria

Awọn ọmọ ẹgbẹ na tun fi ye oloye Awolọwọ pe ọpọlọpọ to di olori ni ilẹ Afrika loni lo ti jiya iru ti oloye Awolọwọ sugbọn ni ikẹhin awọn lo boriti nwọn si segun

Ninu ipade ti awọn obinrin Ọlọja ti nwọn jẹ awọn ẹgbẹ Afẹnifẹre se ni ọjọ Aiku ọjọ keji Osu yi awọn ọmọ ẹgbẹ na rọ Alakoso ilẹ Naijiria Ọlọla Alhaji Abubakar ki o lo ipo rẹ rere lati tete da oloye Awolọwọ silẹ ninu ọgba ẹwọn

Ẹni to si daba na ni olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ti awọn obinrin onişowoni Eko ati agbegbe rẹ iya afin Abibatu Mogaji ninu awọn to tun gbe iya afin Mogaj lẹşẹ ni akowe agba ti awọn onisowo ti ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ọgbẹni S.A Oshodi ati iya afin Akankẹ Lawal t' o jẹ Iyalode ti awọn obirin onisowo ni ọja Awolọwọ ti Mushin Ni ikẹhin awọn Obirin onisowo na tun fi ye gbogbo enia pe awọn ni igbekẹle ninu olori ẹgbẹ Afẹnifẹre oloye Awolọwọ ati adele olori ẹgbẹ na Alhaji D.S. Adegbenro,


BI O BA NI

**Iwe—Titẹ**

FUN

**Lilo nibi Işẹ rẹ tabi orişirişi Iwe Itufọ tabi Ijade Oku**

ATI

**Iwe Igbeyawo**

KỌWE SI ILE—IŞẸ—ẸRỌ ITẸ IWE

**Modupẹ Printing Press**
16, Bamgboşe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌỌKU NI A SI NGBA

IROHIN KO TO AFOJUBA
Oan wa wo lẹẹkan şoşo ko si ri iyato

'BANGBA DẸKUN! KEDERE BẸWO!!






Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ẹ lẹnu on akan bi ọdun kan tabi jubẹ lo awọn egbogi rọbirọbi fun le se Iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ se owo ofo mọ.

Bere fun egbogi awọn ara, Ilu Faranse ti wọn npe ni PORAL ojulowo hanunhanun, a amatase egbogi fun I otutu, Ikọ ọna ofun, Ikọ Igbaaya, I o iil-, Ikọ ti o mọ mu enia tu kẹ ẹbẹ nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lungsa tabi ti o ba nmu enia ru pẹlu.

Bi o ba an Igo kan PORAL yi wa Iwọ na yio ri iva tọ ninu ara rẹ ni kiakia Igbaaya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro "IK " rẹ yio si san ni patapata iwọ yio ma jẹun daradara Iwọ yio si un fọnfọn pẹlu alafia de.

Bere egbogi yi ni awọn orisirisi Egbogi Ikọ miran ni Şọbu awọn:—

NIGERIAN MEDICINE STORES
Tinubu Square, Lagos

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone:- 2287 Nigeria, (Ojalta Paji)

Adedun Chemist
14, Wakeman Street, Yaba
ATI NI AWỌN ŞỌBU
IŞẸ OLODUMARE DISPENSARY
IBADAN

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAW A

No. 753 SATURDAY JULY 25. 1964 (2D)


## Elędę Pa Okunrin Kan

KALABA:— Jirijini da bo gbogbo enia nigbati nwon ri Okunrin kan Ogbeni Okon Harry Akpan okan ninu awon onisowo alafowosowopo ti ilu Calabar nigbati awon enia ri Okunrin na ti Oṣubu lulę larin awon ehnnna ęlędę ti nwon si ti bu Okunrin na ję kakiri ara rę.

Gęgebi irohin lati Owo awon Olopa fi ye wa pe Ogbeni Okon Harry Akpan mura lati lo ba awon ęlęgbę rę Onisowo Alafowosowopo se ipade nigbati o bo si arin awon ehanna ęlędę na lojiji eyiti o mu Okunrin na ṣubu lulę to si fi ori lulę. lęsękęsę na ni Okunrin na di oku awon ehanna ęlędę na si bęrę si faya pęrępęrę.

Opolopo awon ęlędę yoku ti nwon nwa onję lati ję yara sare de ibi ti awon ęlędę yoku wa ti nwon si bęrę si bu Ogbeni Okon Akpan ję kakiri ara

Irohin lati owo awon Olopa fi ye wa pe lęsękęsę ti nwon ti ri pe Okunrin na ko lagbara lati dide mo ni nwon ba tete gbe Okorin na lo si ile iwosan awon Olopa si so pe ko pę dię ti nwon gbe Ogbeni Akpan de ile iwosan lo ba ku patapata.

# Goodluck Ati Awon Elegbe Rę Meji Jare Ejo

EBUTE METTA:- Ni ojo Eti ti iṣe ojo kęrindelogun oṣu yi ni ile ęjo kekere ti Ebute Metta eyiti o dajo awon męta ninu awon olori Osişę ni ojoBo ti işe ojo kętalelogun oşu ti o da awon męta lare ninu ęşun ti Ijoba fi kan won pe nwon şe ipade ode gbangba tun da awon męta silę ni ana awon enia męta na ni Wahabi Goodluck, Nnaemeka Chukwura ati John Alabi.

Ni ojo'Bo ti işe ojo kętalelogun oşu yi ni adele adajo agba ile ęjo na Ogbeni Adetayo Awolesi ni ki nwon fi ofin ipejo gbe Ogbeni Goodluck ati eni to gba iduro rę wa lori ohun to le fa ti nwon ko si fi ara han ni ile ęjo na lojo na-

Nigbati adele Adajo na da awon męta ninu awon olori oşişę na lare lo so ninu idajo rę pe on yio şe ęjo awon olori oşişę męta yoku ni ojo keji. Esun ti nwon fi kan awon męta ti nwon ti ko da silę lakoko na fi kan awon olori oşişę męta yoku eyiti Ijoba fi kan awon olori oşişę na pe nwon lodi sofin iwode gban gba eyiti awon olori oşişę na şe ni ogbonjo oşu karun odun yi.

Awon Olori Oşişę na si tun ba awon Olopa jagun ni ojo ti oro na sęlę nigbati awon Oşişę ati awon Olori won to ti nwon so pe awon yio lo ba Alakoso Ijoba apapo ilę Naijiria lori abayori eto ekunwo Owo-Oşu



Ogbeni GoodLuck

eyiti igbimo Oluwadi Morgan şe ti awon Ijoba apapo ilę Naijiria kuua lati gbe e jade.

Nigbati awon Olori Oşişę ati awon Oşişę nto bo lati ile işę awon Oşişę ni Ebute-Metta ti nwon de ni kereni Iddo ni awon Olopa ba si bere si ni ri kondo nwon tun awon Oşişę na ka titi awon Oşişę si fi nba awon Olopa na nfi ija pęta.

Opolopo awon oşişę ati Olopa lo fi ara gbogbo ni ojo ti rogbodiyan na bę silę eyiti o fa iku okan ninu awon Olori oşişę na ni Ogbeni N u r u Tiamiyu Cole ati alaga Olori awon Oşişę Alhaji Haruna Popoola ti o fi ara pa eyiti nwon si fi gbe e lo si ile iwosna lati lo şe itoju rę. Ni ojo keji ti Ijoba fi ofin gbe awon Olori oşişę na.

## ÀKIYESI

Eyi ni lati so fun eyin onkawe Irohin Imolę pe ITAN EŞUBELEKE ti ogbeni J. O. Shoyinka Opitan Ajiran ilu awon Oku se ileri fun nyin pe yio bęrę laipęyi, itan na yio bęrę si ma jade ninu iwe wa lati ojo Monday ti o mbo yi (eyi ni ojo Aiku ti ise ojo Kętadinlogbon osu yi.

Nitorina se jęki itan na yo o, da itan yi dun pupo o si kun fun ogbon ati oro laakaye itan na yio si gba to ododi ofu męfa gbako ki o tan, beslm ojojumo ni yio fi ma jade.

Ha! itan na pabambari o le go go eniti o ba ka ni o le so, maşe pęki nwon Irohin Itan na fun o maa ka irohin Imolę l'ojojumo, kobo m ji pere ni

## LATI OJU EWE KINI

Nigbati oniwe irohin wa tun bere pe nję awon enia awon eni to wa logba ęwon na le wa ki won bi? Oloye Giwa Omo -Osagie si dahun pe odi igbati nwon ba kowe wa fun lati wa şe abęwo awon enin won to wa logba ewon.

Irohin tun fiye wa pe Alakoso eto ogba ęwon Oloye Giwa Omo Osagie yio şe abewo si ogba ęwon ti ilu Calabar.

nibi ti Oloye Awolowo ti nşe ęwon rę bayi ati pę oşę to nbo ni Alakoso ogba ęwon yio şe abęwo na.

Opolopo awon enia ninu awon to wa l'ęwon ti nwon gbo pe nwon fę gbe awon enia na kuro lo'gba ęwon lo tete lo si tosi ogba ęwon lati le ri awon enia won ki nwon to gbe won kuro l'Eko. Şugbon okan ninu awon oga ti nşe abojuto won ęlęwon so fun awon enia na pe ki nwon ma lo si ile won ati pe ki nwon feti si irohin lati le mo awon enia ti nwon gbe kuro lo'gba ęwon Eko ati ibi ti nwon yio lo.

Gęgębi irohin ti oniwe irohin wa ri gbo lati ogba ęwon l'Eko fi ye ni pe ni agogo meji owuro ni nwon ti ji awon enia ninu awon ti nwon yio gbe kuro logba ęwon Eko pe ki nwon tete ma mura silę fun irin ajo.

Irohin tun fi ye wa pe ko pę dię ti nwon so fun awon ęlęwon na lati ma mura silę fun irin ajo ni awon enu ona ogba ęwon ti Ikoyi, Broad Street ati kirikiri şi silę ti awon Olopa ti o mura ija ogun to si ęgbę awon enu na ti nwon ko won lo si ibudo oko Ofurufu ni Ikęja lati le gbe won lo si awon ipinle meje nibi ti nwon yio ti lo ma şe ęwon won bayi.

Irohin tun fi ye wa pe gbogbo awon Olori ęgbę Afęnifęre męjo na si mura dada pęlu ęrin lęnu titi nwon fi wo oko ofurufu ti yio ko nwon lo sibi ti nwon yio ti şe ęwon won.

Ni ikęhin Alakoso ogba ęwon Oloye Osagie fi ye oniwe Irohin wa pe ti awon enia awon ęlęwon na ba fę wa şe abęwo won pe nwon ni lati koko ti gba aşę tęlę ki o to, to ojo na.


Printed and Published by Modupę Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street Lagos 25/7/64.